Ṣé Wàá Máa Ṣàánú?

Ìtọ́ni: Ibi tí kò sí ariwo ni kó o ti ṣe ẹ̀kọ́ yìí. Tó o bá ṣe ń ka àwọn ẹsẹ Ìwé Mímọ́ tó wà níbẹ̀, máa fojú inú wò ó bíi pé o wà níbi tọ́rọ̀ náà ti ṣẹlẹ̀, kó o sì máa fọkàn yàwòrán ohun tó ń ṣẹlẹ̀. Jẹ́ kó dà bíi pé ò ń gbọ́ bí àwọn èèyàn náà ṣe ń sọ̀rọ̀. Ronú nípa bí ohun tó ò ń kà yẹn ṣe máa rí lára àwọn èèyàn wọ̀nyẹn. Kó o sì máa fojú inú wò ó bí ohun tó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́.
Àwọn tó wà nínú ìtàn yìí: Ọkùnrin Júù kan, àlùfáà kan, ọmọ Léfì kan àti ará Samáríà kan
Ohun tó ṣẹlẹ̀: Ìtàn tí Jésù sọ nípa ará Samáríà kan tó ran Júù kan tí wọ́n ṣe léṣe lọ́wọ́.

1 RONÚ NÍPA OHUN TÓ ṢẸLẸ̀.—KA LÚÙKÙ 10:29-37.

Fọkàn yàwòrán bí ọ̀nà Jerúsálẹ́mù sí Jẹ́ríkò ṣe rí, kó o sì ṣàlàyé rẹ̀.

_____

_____

Báwo ni o rò pé ojú

àlùfáà náà àti ọmọ Léfì náà ṣe rí? _____

aláàánú ará Samáríà náà ṣe rí? _____

Báwo lo rò pé ọkùnrin tó fẹ́ "fi ara rẹ̀ hàn ní olódodo" yẹn ṣe máa sọ̀rọ̀?
(Ka ẹsẹ 25 àti 29.)

_____

_____

2 ṢÈWÁDÌÍ KÓ O SÌ RONÚ JINLẸ̀.

Kí nìdí tó fi ṣeé ṣe kí ẹnu ya àwọn tó ń gbọ́rọ̀ Jésù pé ará Samáríà kan ran Júù lọ́wọ́?
(Ka Jòhánù 4:9.)

_____

_____

Kí ló ṣeé ṣe kí àlùfáà náà àti ọmọ Léfì náà ti ṣe kí wọ́n bàa lè dọ́gbọ́n sá fún Júù tó nílò ìrànlọ́wọ́ yẹn?

_____

_____

Kí lo rò pé ó mú kí Jésù sọ ìtàn kan dípò kó dáhùn ibéèrè ọkùnrin náà tó wà ní Lúùkù 10:29 ní tààràtà?

_____

_____

www.jw.org © 2013 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

3 WO BÍ O ṢE LÈ FI OHUN TÓ O KỌ́ SÍLÒ.

Ṣe àkọsílẹ̀ ohun tó o kọ́ nípa . . .

Ohun tó túmọ̀ sí láti jẹ́ aláàánú.

Bí o ṣe lè fi hàn pé o nífẹẹ́ aládùúgbò rẹ.

4 BI ARA RẸ PÉ:

Ojú wo ló yẹ kí n fi wo àwọn tó wá láti ẹ̀yà míì tàbí orílẹ̀-èdè míì?

Tí mo bá rí i pé ẹnì kan nílò ìrànlọ́wọ́, kí ló yẹ kí n ṣe tó máa fi hàn pé aláàánú ni mí?

Kí ni mo kọ́ nínú ìtàn yìí tó ṣe pàtàkì sí mi jù, kí sì nìdí?

Àbá: Ya àwọn àwòrán tó o lè fi sọ ohun tó ṣẹlẹ̀ tẹ̀ léra nínú ìtàn Bíbélì yìí. Ṣàlàyé ohun tó ń ṣẹlẹ̀ nínú àwòrán kọ̀ọ̀kan.



JW .ORG™

Wa èdà PDF yìí jáde lórí www.jw.org/yo

www.jw.org © 2013 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania